Chief Secretary to the Govt

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. NO. 273. SATURDAY, MAY 5, 1928. 4d

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

NIGERIAN SECRETARIAT 21 AUG 1928



## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos,

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, l o si nję ki o ri aye wu arun mi silę.



Aseru

"AWA O MA JO, AWA O MA YO, NI"

Aga ati Asia (*Flags*) ti Germany lorișirịși wa fun hihaya ni No. 3, Docemo Street, Lagos. Aga ati Asia wonyi dara fun akẹkẹyẹyẹ pupọ, fun Igbeyawo Wolimọ, Ijọ-Odun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere ile Ẹgbẹ, ati orișirịși ohun ayọ miran.

*Terms very moderate.*

For particulars, please apply at :—

EKO-ATODO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

Office :—
No. 3, Docemo Street,
P.O. Box No. 505.
Lagos, Nigeria.

Coffins to suit your Taste

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

# Ero ya wa ra

ADEBOYE ȘOLANKẸ Onișowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-ọkọ, Iṣo lorișirịși, Kọkọrọ (Iṣika) t'ilẹkun ati t'apoti lorișirịși, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọdẹ lorișirịși ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọșan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorișirịși, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-șawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Șọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-iṣe Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ.

**Are you a Mechanic?**—If so you must want Tools, now or soon.

**Do you intend to put up a house?**—Then you will require Builder's Hardware!

In either case you cannot do better than call at

## B. C. Vaughan's "Excelsior" Stores

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and prices to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

## J. C. VAUGHAN

Ti ile ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orișirịși ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilẹkun awọn ile-owo mejeji wọnyi și silẹ fun awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna : bi o fẹ da awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ ọ ni'ya lati ra nibẹ :

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ nṣo, gẹgẹ l'oșe fun ọ lati re yan irin-iṣẹ tirẹ nibẹ ba kanna

Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Atari-Ajanaku lọjọ to ti pẹ : bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ngba kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai ! bi o ri orișirịși Oko ti o ri-ra nibẹ ha yio șe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (*Sawyer*) Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ Agbẹ re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremere ibẹ.

*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Odun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

EJỌ PRINCE EṢUGBAYI ELEKO TI DI RIRO, OGONGO SUNRAKI.

A gbọ nibi ti o ngbe dọsọ pe Kotu Apili Alẹṣẹ Ọba fọnsi Ẹjọ *Prince* Eṣugbayi Eleko ni *Monday* ati *Tuesday* ọsẹ yi, awọn Loya *Prince* Eleko ati ti Ijọba si ki ipọri ọrọ ẹjọ na fun Kotu ni *Wednesday* ọsẹ yi—Idajọ li a nreti nisisiyi gẹgẹbi a ti gbọ fẹnrẹn ọrọ na si.

AJAKALẸ ARUN MI 'GBORO TITI.

Pẹkirẹki ni a ri asia pupa kan ni *Monday* ọsẹ yi ti Ijọba fi si ile kan ni No. 42 Smith Street ti nwọn si fi Ọpa Ọba kan sọ ibẹ: lai ṣiye meji, ko si nkan meji ti o bẹ si ile yi bi ọran bẹ si'le nla bikoṣe ajakalẹ arun eyiti o mu ki awẹn ti o ngbe ile na kuro nibẹ ni ṣaṣa didi; ojo nrọ, ara nsan pa'nia, ajakalẹ arun nja ninu Eko yi kanna! eyi ti jẹ?

AGBAGBA ILU Ẹ DAKẸ NI,

Ofin ṣukuru ti Ijọba nlọ nisisiyi sọ pupọ awọn ọmọ 'le'we di alarinkiri lai ri ṣukuru wọ, ni koi pẹ yi ni a gbọ pe awọn ọmọdekọnrin meji kan ti nwọn bọ wa si ile lati idalẹ lati lọ ere si ile'we giga lọ, kiri gbogbo ile'we giga ti o mbẹ l'Eko lasan lai ri ọkan wọ ninu wọn nitoripe nwọn ti kun, bi o tilẹ jẹ pe awọn ile'we miran jẹjẹ pe ki nwọn mu suru diẹ si boya aye le wa fun wọn. Igi ma da o! ilu ẹ mura si ọrọ Ṣukuru yi nitori ẹhin ọla.

ORI MI YAN ABARI AWIN.

Ni ọjọ *Monday* ọsẹ to kọja ti iṣe ọgbọn ọjọ Oṣu *April* (*30th of April, 1928*) nigbati a nkọja lọ ni ọna Isalọgangan ni ọdẹmọde binrin Ijẹṣa kan ti nta epo pupa bẹrẹ si ke bayi, nigbati o da epo ti nta nu si oju gọta, nipa ijafara to l'ewu, ọdọmọdebinrin yi pantete ko fi ọwọ mu igba epo rẹ, bẹ lo yọ si gọta, ti o pari ọja rẹ iyebiye yi si gọta, ko to fi igbe buruku yi bọ'nu pe a we o; ori mi tan mi jẹ, a we mo rọran, ori mi yan abari awin; ha, ori mi tako mi, mo gbe awe, kini ma ya sọ lule. Pẹlẹ o Ijẹṣa abẹ Ogunraludo arin lọ sin Ọwa Oluyeye pẹlẹ o.

MO RI TO, AWỌN AFI OṢI ṢE AYỌ.

Ni dede agogo meje alẹ ọjọ *Monday* ọsẹ yi ti iṣe 30/4/28 ni a ri awọn ọmọ Jaguda mẹta ti nwọn bẹrẹsi ma le ara wọn kakiri adugbo Oko Awo, laipẹ nwọn fi'ja pẹta, ti nwọn si nlu ara wọn ikankikan, nibẹ ni Ọpa Ọba kan de ba wọn lẹnu ija yi, nwọn si ro ẹjọ pe awọn yọ owo pọnun meji ati abọ (£2 10. 0.) lapo ọkọnrin kan, awọn ara wọn yoku sọ pe awọn ko ni pin on ninu owo na lo mu ija wa, akara ba tun si epo, Ọpa Ọba ko wọn lọ. Ọran re aladugbó, ẹ ma jafara o.

NIHIN, LỌHUN, NIBI GBOGBO.

O ta si wa leti fẹnrẹn pe awọn ero pataki kan yio ti ilu Agbadayigi de si ilu yi ni ọjọ *Saturday* to mbọ; a gbọ wipe ti nwọn ba de, nwọn yio tatare lo si ọdọ Alaṣẹ Ọba (*Administrator of the Colony*) lati ṣe alaro nipa ọran "owo ori" ti Ijọba ndaba lati gba. Njẹ bi o ti mbẹ ni ile bẹ lo mbẹ loko, o kari aiye—ọmọ Ajalọrun, Edumare yio to bi o ba ti tọ loju Rẹ.

DAN-BARAWO!

Ọran o suwọn ni irọlẹ ọjọ Satide ijẹjọ ni Ita Palm Church ni eti ile Lọya Abayọmi,

nigbati a ri wọn ritiriti ti wonpapa ọkọnrin kan fa ọbẹ agboyi yọ ti o si nda gbogbo adugbo ru: a gbọ wipe Dan-barawo ọkọnrin na lọ fọn wọn ni owo ni ṣabu awọn Kọra, ti o ba ngbo pã! põ!—igbaju, igbamu nũ; ki a na da lọ po po-po, gbirihan ni ọkọnrin yi ṣubu bi oku ọmuti, didide ti o dide o ṣiyan ko duro gb'ọbẹ, gbogbo enia rọ girigiri o di bi o lọ ya mi, nigbẹhin a gbọ wipe ọwọ awọn Akẹran tẹ ẹ, nwọn si fa ni tẹ-tẹ lọ si ṣabu wọn.

AWỌN ỌFỌN WỌ'LU, KẸ SUNRAKI.

Lọtun-losi li a ngbọ ibosi ole laseko yi, bẹ si ni a ngbọ wipe awọn barawo na nfọ wọn ni ṣabu ati ile kakiri nisisiyi, a si ro pe boya ọdun Ileya ti o mbọ yi lo mu sababi ti ọgọrọ awọn ole ni ilu ni aseko yi wa; yio dara bi olukuluku ba nṣe abojuto ṣabu ati ile rẹ daradara laseko yi, a si tun bẹ awọn Olotu Ọpa Ọba ki nwọn jọwọ ki nwọn maṣai ba wa fi oju agba si ode fun wa—A yin si wa leti pe nwọn ko ọkọnrin kan nile lọ tefetefe lapa adugbo Ṣogi Arọlọya, tobẹ ti nwọn fi yi si kombo, afi aṣọ ibora nikan ti a gbọ wipe o ku oluwarẹ ku; eyi ha nkọ?

---

LAGOS TOWN COUNCIL.

---

Lati ọwọ Kekere Awo.

---

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

Iṣẹ wo ni awọn "*Lagos Town Council*"—Igbimọ ilu ni lati ma ṣe larin wa? ibere yi ni a kọkọ fẹ gbe siwaju wọn na!

Bi nwọn ko ba mọ ọ, tabi ti iṣẹ wọn ko ba ye wọn daradara, a ni lati fihan wọn, nitori o dabi ẹnipe nwọn ma nda ara wọn riboribo loju wa, nigbamiran ti nwọn ba ni awọn ntun ilu ṣe ẹwẹ ti nwọn ba ni awọn nṣe eto ilu.

Bi a ba nperi aja a o ma peri ikoko ti a fi se e, gbogbo ohun to nlọ nipa titun ilu tabi adugbo ṣe, *Municipal* lo gbe ẹru wọn k' ari, ṣugbọn Municipal abẹ *Lagos Town Council* lo wa, orukọ mejeji ọkan lo jẹ, abẹ Ijọba si ni orukọ mejeji wa, ẹmi abata lo nmu odo nṣan, agbara Ijọba ni *Lagos Town Council* fi nmi, nitori Ijọba lo jẹ ogongo baba ẹiyẹ-k'ẹiyẹ fun wọn.

Nitotọ *Lagos Town Council* le wa firidefiri, ṣugbọn gbogbo ohun ti nwọn ba nṣe nipa agbara ni, a le kuku sọ wipe Ijọba lo nṣe atilẹhin fun Municipal lori gbogbo eto ati ẹtọ ti nwọn nṣe si ilu.

Ti a ba nfẹ atunṣe ni apa kan ilu Ijọba ni a ni lati kọ ke si, siwaju ki a to wa pari rẹ sọdọ awọn *Lagos Town Council* awọn ẹniti Ijọba yan lati ma ṣe eto atunṣe ilu, nipa eyi ni a tiṣe sọ siwaju pe bi a ba nperi aja a o ma peri ikoko ti a fi se e? ẹrọ ti o kan awọn *Lagos Town Council* ni a fẹ sọ nisisiyi ṣugbọ bi awọn Ijọba papa ba fi eti kọ ninu rẹ ko ni laifi kankan arara.

Ohun ti o yẹ ki Ijọba papa gbọ nipa rẹ ni: Bi awọn Alatunṣe ilu ba nran aṣọ awẹ kan ko buru lati fihan wipe aṣọ awẹ kan ni nwọn nran an, ṣugbọn iyẹn ko ni ki a di ọga tailor, nitori a ko to arara lati kọ awọn Alatunṣe ilu ni iṣẹ aṣọ riran, ṣugbọn gbogbo atunṣe ti nwọn ba nṣe ni ilu, ko ni lati lọ wipe bayi ni nmaṣe nkan mi, irufẹ ero bẹ ko le mọyan lori rara, ikosi si atunṣe kan ti o le mu wa si arin ilu fun anfani ati alafia ilu.

Gbogbo ohun ti awọn *Town Council* nṣe laseko yi fun rere ati atunṣe-ilu le dabi ẹnipe o nmu owo dani, ko dabi igba kan ti gbogbo rẹ jẹ ofẹ larin ilu yi na, bi o ti jẹ wipe gbogbo nkan isisiyi ko lo lasan, o yẹ wipe ki o ma lọ ni ajambaku bi?—idi rẹ ti o fi ma nmu awọn ẹniti o nkọ iwe sinu iwe-irohin sọ lẹkẹkan pe, ibiti oyinbo ba nlo si ni ilu yi ni irọrun pupọ ju ibiti awọn enia dudu ngbe lọ.

O le jẹ bẹ, o si le ma jẹ bẹ, amọ o jọ gate ko jo gate o fi ẹsẹ meji tọ loju ti awa, bi ko tilẹ ri bẹ dan-dan, ipo miran ti awọn enia dudu nlọ si ni arin ilẹ yi ko ni anfani kankan lara arara, eyi si lo ohun to le mu wa sọ wipe nitotọ ibiti awọn oyinbo nlo si ni arin ilẹ yi ṣanfani nigba nain ju bomiran ti awọn enia dudu ni ilẹ yi nlo si lọ.

Mo ṣe ranti ni ọdun kẹta ọhun 1925, nigbati ilu ati Ijọba npalẹ mọ silẹ de Arẹmọ-Ọba (Prince of Wales) lati wa bẹ *Nigeria* awọn ilẹ enia dudu wo ti Arẹmọ-Ọba si fẹ fi ẹsẹ kan ya ibi pa, o dabi ẹnipe ọgbọn ẹwẹ ni Ijọba fi le awọn ara ilẹ yi ti nwọn nta ọja kuro ni Ebute Ẹhingbẹti.

Ṣugbọn ohun ti a ngbọ nigba na ni wipe nitori arun Ekute ti o nja ni ilu, ki o ma yọ foro ni eti Ebute-Ẹhingbẹti, ki nwọn ma ba luwẹ lọ ba ọkọ Arẹmọ-Ọba ni agbami nigbati ọkọ rẹ ba wọ ilu nitoripe Ajakalẹ-arun, eyiyi ni arun-ekute ko ṣai wa ni ilu ti o nja laseko na—tobẹ ti fi jẹ wipe agbara kaka ni Arẹmọ-Ọba fi wa sihin, ati pẹlu kini ki a ti pe e, ọran buruku t' on-tẹrin.

Wara-were ti awọn ara ilẹ yi fi agbara ati irọju kuro ni Ebute-Ẹhingbẹti ni awọn Ijọba gbin ododo (flower) lasan-lasan sibẹ.

Ko si iregbe ti o ku ti ilu ko wi tan nigba ti awọn ara ilẹ yi ko wi tan, ti Ijọba ko tilẹ mọ wipe

...an nşe iregbe lori aroye wọnyi ni a fihan wipe ...n ero Ẹhingbẹti ti ni anfani pupọ ni Ẹhingbẹti ...i ti nwọn le pa giri kuro mbẹ—o dabi igbati ...ngbe inu ile kan titi yala o haya ibẹ tabi o tilẹ ...e lasan, ti oluwarẹ ko si şe ohun aşe-maşe kan, ...jẹ ohun işoro gidigidi lati şi oluwarẹ nidi pada ...o tilẹ ni sababi kan ti oluwarẹ le fi kuro ninu ...na, bẹ gẹgẹ ni ọran na lọ gan—bi oluwarẹ tilẹ ...a lo lo si ibomiran, ile ti enia fi apandodo gbe, ...wo lo le gba fi jẹ itẹlọrun ?

Lati igbati ọpọlọpọ awọn Ero Ẹhingbẹti yi ti ...ro nibẹ ni ọja wọn ko ti lọ dede, nwọn le jẹri ...eyi.

Nitotọ Ijọba fun wọn ni Ebute Alakoro lati fi ...po Ẹhingbẹti lati ma ta ọja wọn, şugbọn sibẹsibẹ ...o dabi alara fun wọn, nitori Ijọba ko gba wọn ...are lo gẹgẹ bi anfani ti nwọn ni lẹhingbẹti—awọn ...yinbo-onişowo papa si le ranti pe nigbati awọn ...Ero Ẹhingbẹti nta ọja nibẹ, Ẹhingbẹti ni lari julọ, ...a jẹ sanmani yi ti gbogbo rẹ di nkan miran nipa ...ta ọja fun wọn.

Ori ko tilẹ wu ọpọlọpọ awọn ẹlomiran debi ti ...e le ba wọn ko lo si Ebute Alakoro; awọn Ero Ẹhingbẹti ti a le lọ si Alakoro nijọ kini nibo ni ...a wọn tun wa loni? nwọn mbẹ ni Oke-arin nisisiyi, gbogbo Buka ti awọn *Lagos Town Council* ...ọ, a gbọ wipe nwọn ngba owo rẹ lọwọ wọn, şile meji-abọ li a si gbọ wipe nwọn san fun Buka kan, ...o si daju pe ẹniti ko san owo kole lo ibẹ lọfẹ, ...iyafi ẹniti o ba ni ẹniti o le ba pẹmọ sibẹ ti oluwarẹ ko fi ni sanwo, şugbọn Buka ti o mbẹ ni Oke-arin nisisiyi pẹlu owo ni şile meji-abọ loşoşu.

Ki a tilẹ ko ti wipe nwọn nsanwo, nwọn ko sanwo kuro; a gbọ wipe awọn Town Council kọ Buka silẹ na, mo ro wipe nwọn gbagbe wipe ...igbati nwọn ni awọn fẹ şoju-agbara si ọja Ereko ni Idumta, ti nwọn ni ki awọn ero ọja Ereko lọ ko Busọ si Oke-arin yi (eyiti ẹnikan nlu agogo kere kakiri nigbana pe Ibikunle Akitoye ni ki awọn ero Ereko lo kọ busọ si Oke-arin nitoripe awọn Munisipa fẹ lo ibẹ) nwọn nsọ wipe Oke-arin ki işe ibi ti enia le joko lati ma ta oja, nitori ipo ti o wa ko dara arara, nwọn si fi nhan Munisipa nigbana wipe o nfẹ ọpọlọpọ atunşe gidigidi, ki enia to le lo ibẹ.

Awọn Ẹgbẹ Dẹmọ dide si ọran yi laseko na, nọwn lọ ba awọn Alatunşe-ilu ni Munisipa, nwọn si sọ wipe awọn ko fun ẹnikẹni ni aşẹ lati pa ni ilu, şugbọn awọn nfẹ şe oju-agbara sibẹ nitotọ ati pẹlu awọn nfẹ tẹ Titi nitorina ki olukuluku mura lati ma pa ilẹ mọ, barafo nigbati awọn eşişẹ ba de ibẹ ki nwọn ma ba di wọn lọwọ fun işẹ wọn; awọn ẹniti ẹgbẹ Dẹmọ yan lọ fun ọran yi si ni ki oyinbo awọn Alatunşe-ilu fi gbogbo ọrọ yi sinu iwe, ki o ba le da awọn ẹniti o ran wọn nişẹ loju nigbati nwọn ba ma fi abọ fun wọn oyinbo na si şe bẹ nitoto—awọn ọmọ ẹgbẹ si gbọ gbogbo bi nkan na ti ri nigbati awọn—olotu ẹgbẹ fi abọ fun ọmọ-ẹgbẹ ni ipade Gbo-gbogbo ti nwọn şe ni igba na, pe kufi ni agogo ti nwọn gbe si ode, nda a ẹnikẹni ko bẹ ẹnikan lọwẹ agogo kere! pe ki awọn ero ọja Ereko fi papanleke lọ si Oke-arin —imado iba şe bi ẹlẹdẹ a ba lu jẹ, bi ko ba si aiye oyinbo *Igesi* ti a wa yi, bi ẹru ba jẹ Ọba ni ilẹ yi enia iba ti ku ọkan—igi iba da loko.

Gbogbo awọn ẹniti o nşe wahala ni ilẹ yi pe dan-dan dan-dan ki awọn ero-ọja Ereko lọ gba busọ ni Oke-arin, nwọn ko ranti pe Ọba Kosọkọ lo lọ mu Iga si Ereko ni aseko aso on pẹlu aburo rẹ Ọba Akitoye, ati pẹlu ki işe ohun itosi nihin ni ọja Ereko ti mbẹ ni ibẹ, eyi ko jẹ ohun abuku ti o mu işoro dani lo ju wa lati ri wipe nwọn pa ọja Ereko rẹ nitori a lẹ ,şe oju-agbara kan lasan

Lẹhinna ẹwẹ tani jẹ jẹki ẹbi tabi ara on kan lọ tẹ gẹngẹ ẹsẹ si inu abata 'rọfọ ti o wa ni Oke-arin ni ibiti nwọn fẹ şe busọ si fun awọn ero?

Nwọn gbagbe lati şe atilẹhin de ibẹ wipe gẹgẹ bi awọn ti nsa agbara pe ki a le ko ọja Ereko lọ Oke-arin yi, nitorina o tọ, o yẹ ki awọn Munisipa tun ibẹ şe gẹgẹ bi nwọn ti le şe ibi ti oyinbo le lo si gẹgẹbi iru ipo ti Oke-arin na wa.

Pẹlu bi ilu ti fi oye han wọn to pe ki nwọn le tun Oke-arin şe fun anfani lilo ki a tilẹ ko ti wipe awọn ero ilu yio ma lo ibẹ nwọn ko lo ibẹ kuro

Oke-arin ko wọ tẹlẹtẹlẹ fun ararẹ, nitoripe ko si ẹniti o le duro ni ibẹ lasan fun bi wakati melo kan ti ko ni şe alabapade lakuregbe lagbara, ambọsi-bọsi, ki a wa sọ wipe ki enia wa joko sibẹ lati ma ta ọja—a fi ẹniti o ma lọ si ile Dokita apapandodo, nitori o daju pe aisan ko ni pẹ ma kọlu enia nibẹ.

Şugbọ sibẹsibẹ, awọn Town Council fi ọgbọn ati ẹtọ le wọn kuro ni Alakoro nisisiyi, nwọn si tị da awọn lọ si Oke-arin ijọ kini lati ma ta ọja wọn.

A gbọ wibe awọn Town Council şe busọ fun awọn ara ilu ni Oke-arin na, ẹwẹ a si ri wipe nwọn ti le wọn ni Alakoro ati ni opopo Victoria lọ si Oke-arin na fun tita ọja wọn, a si gbọ wipe busọ na ijowo ni ki işe ijọfẹ, bẹni a si gbọ wipe şile meji-abọ ni ojule-busọ kọkan fun hihaya ẹniti ko si le san şile meji-abọ loşoşu aiyaşebi ko ni busọ i fi şe, ẹ ko ha ri gbogbo ọran na bi o ti nlọ si?

Şugbọn melo ni eto atunşe ti nwọn şe sori busọ wọnyi, ọpa lasan ni nwọn fi ka nwọn? Nwọn si şe patako pẹpẹ kekeke si inu wọn? Nọwn ko rẹ wọn ni Simẹnti *Cement*, bẹni nwọn ko kan wọn ni akanpa debi ti nwọn ma şe ilẹkun sinu rẹ fun wọn, şugbọn nwọn ru iyẹpẹ sibẹ, ki nwọn to bẹrẹ si işe awọn busọ wọnyi si ori ilẹ; ẹnikẹni ti o ba fẹ o le mọ ti ikawọ rẹ ni ogiri ki o si şe ilẹkun sinu rẹ ti o ba wu u, iyẹn ko kan Munisipa arara, iyekiye ti ẹnikan si le na, Munisipa ko ran ẹnikẹni nişẹ, bi oşu

ba sa ti pari, ti olukuluku wa san owo-buso ti ɔ gba a.

Wayi o, busọ wọnyi elo lo pari rẹ bi o ti wa ?—elo ni a ro wipe o le tọ bi a ba pe awọn Kafinta nisisiyi pe ki nwọn sọ iye ti o le pari rẹ, ti o ba jẹ wipe awọn ara ilu fun ara wọn ni nwọn ni lati ṣe inawo busọ na—gbogbo owo ti nwọn yio ma ri-gba lori busọ kọkan lọdun o jẹ ponun kan abọ, ti o din, ti o yọ.

Ẹ wa ẹ jẹki a bi awọn "*Town Council*" tabi Munisipa wayi--tani ẹniti o le joko si busọ Oke-arin ni aseko ojo lati ma ta ọja—Munisipa ko ṣai mọ irufẹ ipo ti Oke-arin wa tẹlẹtẹlẹ ? bi ẹniti ara rẹ ko le daradara ba de ibẹ lati ra ọja ati lati wa ni ibẹ lati ma ta ọja, ilẹ tutu le mu ara enia le ni tabi o le mu ailera ba enia ? ẹniti o si nsa fun ailera ti ko si le wa si busọ tabi ibiti a pese fun wọn ṣ i Munisipa le ba wọn mọ ọ wipe nitori pe nwọn ı o lo busọ w n nitorina awọn ko ni gba owo busọ ti nwọn haya ? gbogbo nkan nfẹ ero pataki.

Ilẹ *Sangrouse* lo wa ni ibẹ yẹn,..Nigbati Ijọba fẹ fi ibẹ ṣe Bareke *Barrack*, ki lọṣe ti awọn *Town Council*" tabi Munisipa kò ṣe ibẹ ni ile ọpa—*bamboo* fun wọn, ki nwọn to mɔ ọ ni ogiri ti nwọn si ṣe ibẹ toni-toni bi ile oyinbo ? o ha jẹ wipe nitori awọn ẹniti o mbẹ labẹ Ijọba ni Ijọba fẹ fi si inu Bareke wọnyi bẹ ilẹ Sangrouse ko tilẹ dara arara to ilẹ Oke-arin—a si mọ irufẹ ipo ti ilẹ mejeji wa yi ri, bi awọn "Town Council" ba kuku sọ wipe ki nwọn ma san bi ṣile kan abọ tabi ṣile meji fun owo-ilẹ lasan loṣoṣu ki Ijọba si jẹki awọn Alatunṣe-ilu tun ibẹ ṣe fun wọn daradara, yio fẹrẹ san diẹ loju wa ju atunṣe, ti nwọn ṣe si ibẹ nisisiyi lọ.

Nitorina a bẹ awọn ALATUNṢE-ILU, ki nwọn ti itori ilera ati alafia fi ero pataki si iṣẹ busọ ti nwn pese silẹ fun awọn ara ilu si Oke-arin

## ỌLỌLA DOKITA CAULCRICK.

Ni iwoyi ijẹfa ọdun keji (1926) ni awọn ilu Ẹgbẹ Dẹmọ yan Ọlala Dokita J. A. Caulcribk ni Aṣoju-ilu Eko si Igbimọ Aṣoju-ilu Ijọba dipo Ologbe Ọlọla Lọya J. Egerton Shyngle.

Iṣẹ ribiribi ti Ọlọla Dokita Caulcrick ṣe fun ilu ni Igbimọ Aṣofin o ni iye lori, iyẹn ti o ba jẹ wipe owo ni ilu nsan fun ẹniti nwọn ba fi si ipo-nla, iṣẹ rẹ kun ilu loju pupọ gẹgẹbi o ti jẹ wipe o fi gbogbo aniyan rẹ duro girigiri lat ja fun rere ilu de opin agbara rẹ—a tọrọ ẹmi ati alafia fun u ki Ọlọrun jẹki o le mu iṣẹ rẹ dopin fun ilu, gẹgẹ bi a ti mọ wipe ọpọlọpọ awọn enia lo nja fun ipo nla yi lati bọ si, ti Ọlọrun ko si pe ti wọn ni bẹ nitori Ọlọrun jẹ Ọba ti O mọ ohun ti o nṣe daradara.

Dokita Caulcrick ma ba iṣẹ rẹ bọ bi o ti mbọ yi, atilẹhin mbẹ pẹlu rẹ, fi gbogbo ododo rẹ le Sati lọwọ—Ọba na lo fi ọ ṣe, ba 'nu sọ ma ba enia sọ--enia o si mọ aiye ti di eke—Didibo fun awọn Aṣoju-ilu ku oṣu bi marun si nisisiyi ki Ọlọrun ma jẹ ki a ri dasi o.

Emi ni ti nyin nitotọ,

KEKERE-AWO.

---

## ORI III.

## IWA—ẸGBẸ KIKO ATI APẸRẸ.

(*Translated from "Character by Dr. Smiles"*).

APA KEJE.

---

Itara iwa ki iṣai ni agbara lati mu awọn ẹlomiran ni itara. Ọna ãnu tabi ifẹ ni o ngba ṣe iṣẹ, o si jẹ ọkan ninu awọn ọna pataki ti iṣe iṣẹ lara ẹda. Onitara alakanloju enia a mu awọn ẹlomiran gba tirẹ.

Apẹrẹ iwa rẹ a ma ran ; a si mu ni fi ara we. A dabi ina manamana tabi ojiji ti iyi ni ni gbogbo ara—a wọ inu ara awọn ti o wa ni sakani rẹ lọ, a si mu ki nwọn ma bẹ ina yẹri.

Nigbati opitan Dr. Arnold nsọ nipa iru agbara yi eyiti o ni lori awọn ọdọmọkunrin, o ni, "Ki iṣe kiki ti ọgbọn rẹ, ẹkọ iwe mimọ rẹ tabi ẹnu rẹ ti o yọ nikan ni o mu wọn lọkan : ṣugbọn ti ọkan ifẹ eyiti wọ ni lara, ti o fi nṣe iṣẹ laisimi laiye—iṣẹ ti ko ni alèbu, ti o ni irinlẹ, eyiti o si nfi ibẹru Ọlọrun ṣe nigbakugba—iṣẹ ti a da silẹ nipa mimọ riri iṣẹ."

Irufẹ agbara yi lọwọ ọlọgbọn, a mu ni ni igboya, a fun ni ni itara a si mu ni fi ara ẹni jọsin.

Ki a fi tọkan-tọkan gba fun iwa awọn enia kọkan bayi—iru eyiti a ko le ni fun akojọpo enia—ni ima mu awọn akọni ati awọn ẹniti ifi ẹmi wọn lelẹ fun ire ilu wa. Bayi ni a ri i pe titọju iwa ẹni a ran awọn ẹlomiran. A fun awọn ẹniti o ba wa labẹ rẹ ni agbara, a mu wọn sọji, a fun wọn ni okun.

Gbogbo ara ni awọn oniwa rere fi ntan agbara ka, ki iṣe kiki pe nwọn a lo agbara nikan ni, ṣugbọn nwọn a fi agbara fun awọn ẹlomiran pẹlu.

Bayi ni a ri i pe Dante gbe ọgọrọ awọn enia nla dide lẹhin rẹ—Petrarch, Boccacio, Tasso, ati ọpọlọpọ awọn miran. Lati ọdọ rẹ ni Milton ti kọ lati farada iṣọkuṣọ awọn enia ti o nsọ aidara si i lara ati yẹyẹ nigbati ayida de ; ni ọdun gbọrọ lẹhin eyi, nigbati, Byorn ranti Dante labẹ aba ni Ravänna, eyi mu lati kọ orin ti o dun ju gbogbo awọn eyiti o ti kọ ri lọ. Dante fi okun fun awọn ti o nṣe iṣe-ọna amọran ni Italy—Giotto, Orcagna, Michæl Angelo ati Raphæl. Bẹna si ni Ariosto ati Titian jumọ fun ara wọn ni okun, ti ọkan si gbe ogo ekeji yọ.

Awọn ẹni nla ati awọn ẹni rere a fa awọn elomiran si ti wọn, nwọn a mu ki araiye wulẹ gba fun wọn. Gbigba fun awọn eniwa rere, a mu mi ni ọkan rere, a da ni silẹ lọwọ igbekun iwa pe awa nikan ni o gbọn ju, eyiti iṣe ọkan ninu nwọn ano ti idi ni lọwọ lati hu iwa rere. Nigbati a ba nranti awọn enia ti o jẹ pe nipa ọgbọn tabi ero rere wọn, tabi nipa iṣẹ nla ti nwọn ṣe, ni a fi mọ wọn a dabi ẹnipe iranti yi mu ọkan wa kun fun ero rere, a si dabi enpe gbogbo ero ati aniyan wa jẹ rere.

Sainte-Beuve ni, "sọ fun mi tani oluwa rẹ ti iwọ gba fun, ngo si sọ fun ọ iru enia ti iwọ papa jẹ, ngo sọ fun ọ bi, oye ori rẹ ti to, iru ẹwu ati irufẹ iwa ti o ni.

O ha ṣe pe awọn enia jatijati ni iwọ gba fun bi?—Bi o ba jẹ bẹ ni, enia jatijati ni iwọ na O ha ṣe pe awọn ọlọrọ ni iwọ gba fun bi? Bi o ba jẹ bẹ ni, njẹ ẹni ti erupẹ ni ọ, elerupẹ.

O ha ṣe pe awọn olorukọ tabi awọn onipo ni iwọ gba fun bi? Bi o ba jẹ bẹ ni, njẹ alahọn poni-poni ati akobẹrẹ fun awọn onipo ni ọ.

O ha ṣe pe awọn ọlọtitọ enia, awọn akọni ati Omoluwabi ni o gba fun bi? Njẹ iwọ papa jẹ olotitọ akọni ati Ọmọluwabi enia.

Nigba ewe nigbati a nkọ iwa, ni a ni okan ki a ma gba fun enia ju. Bi ba ti ndagba si, àṣà a di ara ẹni; nigba pupọ si ni "aika ẹnikan si" a di àṣà ẹni. Nigbati ọmọ ba wa lọdọ, ti ọkan rẹ si ṣi silẹ fun ẹkọ, o yẹ ki a ṣe āyan kikọ ọ ni ẹkọ bi a ti igba fun awọn enia ti o jẹ ẹni rere; nitoripe bi ko ba gba ti ko ba ka awọn enia rere si—bẹni ọmọde ki iṣai ni awọn ẹnikan ti nwọn a ma wo bi akọni—ọna ati tẹle awọn enia buburu ko jina si wọn.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

---

ETI ỌBA NILE ETI ỌBA L'OKO

Lati ọsẹ to kọja ni okiki ti nmi igboro titi pe Oloye Ọbanikoro ati awọn isangbe rẹ nmura lati gbọlọfẹ lọ si ọna ilu oke titi ọjọ mẹta.

## FORTHCOMING MARRIAGE.

The marriage between Miss Stelle Ibironkẹ George daughter of Mr. J. S. George, Dispenser Medical Dept, Oshogbo and niece of Rev. J. E. George of Ebenezer House, Iṣabọ, Abẹokuta, and Mr. Samuel Ọmọbọla Akinọla, Clerk P.W.D. Lagos, is announced for Thursday next the 10th instant.

---


INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atupo ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

---

## To Lease.

A House at No. 151 Upper Street, Lagos.

Iso ti o wa ni Oke-Arin jẹ *pound* kankan ni ọdọdun kiṣe oṣoṣu.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, MAY 5, 1928.

## "T'ỌLỌMỌ KAN LO ṢORO, KONKO LA WA ṢOJU O, KONKO."

Loju pupọ enia o dabi enipe orin ti Ijọba nmukọ nisisiyi leyi, nitori ko si ẹnikan ti yio ri bi awọn Onisẹ-Ọba oni Khaki ti nwọle wọ'de kiri pin iwe owo asingba, ti nwọn nmu kiri ti ki yio sọ pe họwu bi a ti nki ti a si nsa, pe "ye ye o nlọ o, onisasun ẹran", sibẹ Ijọba ni awọn ko ti mọ ẹniti o ku; ọrọ yi ko se lori owo asingba ti Ijọba nnurimọ lati gba lọwọ Eko ati awọn ilu agbegbe rẹ lodunni bi nwọn fẹ bi nwọn k...; lati ọjọ ti ofin Gẹsi ti wọlẹ bi Ṣango ni ilẹ yi, ẹnikẹni le jẹri si otitọ yi pe ko si irufẹ inira ti o farahan l'Eko bi irufẹ inira ọdun yi ri, a ko tilẹ mọ pe a nyọ ni nigbati labari owo omi ko ṣe owo omi turuku ni igboro ilẹ yi niwọn ọdun mejila sẹhin.

Ere ilaju ni Eko nje loni, a ko bu omi s'ẹnu sọ, ti a ba wipe akoko igba ti awọn baba wa wa l'oko wọn pẹlu awọn aya, ọmọ, ati iransẹ wọn sanju akoko ode oni lọ; ẹ wo ilu ti ko bi o ti ri ninu igba ti a wa yi, igbese ni on igbese, Ile-ẹjọ Kekere ati Ganran kun tẹtẹ fun idajọ ti a nda fun awọn ti ẹsin ọ̀wọ̀ ti gbe ṣubu; awọn igiripa-kọnrin di alairiṣẹṣe, awọn ole fẹrẹ le ji enia gbe ni ọsan gangan kilo tun ku, kilo mu gbogbo eyi wa bikoṣe ilaju alaju ati iwa ọdaju gbogbo? Nitotọ ilẹ kan ko mọ ki awọn oni-ṣabu ọja tita ma ṣi, ṣugbọn ohun ti pupọ enia ko mọ ni pe pupọ awọn onisowo lo ti da bẹnu lai ṣe ẹja Kuta, awọn Oyinbo onisowo miran ntile tọna lọ joko ti awọn agbẹ ati awọn ẹlomiran ti nwọn nṣiṣẹ ekuro l'oko lọrun lati ra lọwọ wọn, kaka ki nwọn mu ọja na wa si Eko. Owo ti Ijọba si ngba lori owo ekurọ lo njẹ on; ifoya si wa fun ẹnikẹni pe bi nkan ti nlọ si nisisiyi, papa ni igboro ilẹ yi, ọpọlọpọ oku le sun si ita fun ebi inu, ti yio han awọn miran lemọ; njẹ ẹnu ko ha ni ya nyin pe ọgọrọ onile ọlọna miran lo ngbe igba "yara sulu lai" lalalẹ, ti nwọn si nlọ si adugbo ti awọn enia ibẹ ko ni ifura si irufẹ ẹni ti nwọd jẹ: ewo ni ọkan ti o gbun Ijọba ninu eyiti a ka silẹ bõro yi, o di ẹmelo ni ẹ ri ki Oyinbo kan ma rare tabi ki o ma yajule tọrọ tọrọ sisi ni ilẹ yi ri? Oyinbo kan onipo nla ko ha sọ ni ọdun pupọ sẹhin pe oko itẹjẹ wọn ni ilu Nigeria jẹ fun wọn bi? Njẹ a bere, tiwa kọ lo ṣoro kọ ni owe ti Oyinbo yi npa fun wa bi? Nitotọ bi a ti nwi lọwọlọwọ yi a ri awọn ti nwọn nfi tọtun tosi wọn ngbọn owo lojolumọ, ti nwọn si ṣoṣin, ti nwọn nṣora, ti nwọn ko si mọ bi ebi npa ẹlẹgbẹ wọn, tabi bi nwọn yo bi nwọn ko yo: bẹni nkan ri, ika ko dọgba, ṣugbọn awọn ti ara kini nwọn yio jẹ kini nwọn yio mu, ile wo ni nwọn yio ri gbe, nkan lode eni larin Eko lo pọ ju.

Ọpọlọpọ ọmọ lo di "ọmọ Jaguda" ọsan gangan nigbati ko si obi tabi ẹbi ti o ma bikita fun, ti o si kan soju kan pe bi o ti le ri ki o ri; tani anu irufẹ awọn ọmọ bẹ ki yio ṣe? Loju awọn ẹlomiran o dabi ẹnipe ara ti o wu Ijọba Gẹsi ni nwọn nfi wa da nipa ofin lilelile miran ti nwon nlo ti a o bẹbẹ pe ki nwọn dẹ fun ni ṣugbọn ti o jẹ pe nigbagbogbo ni a nyin igbado sẹhin igba: kaka ki a sun kaka ki a tẹwọ adura pe ki awọn oluwa wa yi le dawọ inira muwa-muwa yi duro, nṣe ni pupọ nhuwa ọlọmu da ọmu iya rẹ gbe, a ko ni ye sọ nigbagbogbo pe nipa owo asingba ti Ijọba nfẹ fi agbara gba lọwọ Eko yi, "ọ̀wọ̀ ẹru" sisin to tun ju eyi lọ ko si mọ, ṣugbọn

Malu ti ko ni 'ru,
Ọlọrun ni nle eṣinṣin fun.

---

### Thanks for Sympathy.

Mr. & Mrs. Adeniji Olugbile hereby return their sincere thanks to all those who either by personal calls, letters, telegrams or otherwise have expressed sympathy with them on the occasion of the death of their beloved daughter FLORA AGBEKE, who breathed her last at their residence Denton Street, Ebute-Metta, on Sunday, the 22nd April, 1928.

# ATAREDE ATAREDE KA GBỌ TI JESU RE MO MỌ.

### APA KETA.

[WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI AJANAKU.]

...berẹ f'oji,

